Irohin Yoruba

## ỌRỌ OLOTU

### Ẹ gbọ ki ẹ si gba

YORUBA ni "ti alagbẹdẹ ba nlu irin lemọ-lemọ ki a mọ pe aami wa nibẹ". Nitorina ti a ba ntẹnumọ ọrọ kan fun nyin nigbakugba ki ẹ mọ pe nkan kan t'o pataki julọ n'o wa nibẹ. Ni ọsẹ ti o kọja a sọ fun nyin pe ki ẹ mọ ẹ ni iṣẹ iṣelu nyin akoko lati lọ fi orukọ silẹ fun idibo. A si sọ aseko ti ti Ipinlẹ kọọkan yio bẹrẹ ati ti -io pari.

OHUN ti o mu wa ma a tẹnumọ ọ ni pe, ogun-iṣelu ni o wa ni iwaju wa lati ja ni ọdun yi. Ọna ti a si le gba fi jagun ṣegun na ni ki a dibo fun awọn Ẹgbẹ Oṣelu ti a ti ri iṣẹ ti nwọn ti ṣe si ilu ni rere ki a si kọ awọn Ẹgbẹ Oṣelu ẹlẹtan, awọn adabamalẹṣe, awọn aturọta bi clubọ silẹ. Ki a si to ri aye a ti dibo, a ni lati kọkọ fi orukọ silẹ fun idibo.

NWỌN ni "Bi oriṣa ko ba le gbe ni ki o maṣe yọ ni ni ike". Ti a ko ba ṣọra gidigidi lati yẹra fun awọn oṣelu ẹlẹtan, nwọn a ti ajaga ipọnju bọ gbogbo ara ilu lọrun, awọn paapa a si ma a wa ṣe bi ọba. Ṣe ẹ kuku mọ wọn pe "Nigbati nwọn ba fẹ gba awin akara ni nwọn i ma a ṣe oju anu ti nwọn ba yo tan, nwọn a di ọmọ-ọba."

BI nwọn ba de aye Alakoso Ijọba tan nwọn a bẹrẹsi gun mọto bọọli. Bi o tilẹ ki wọn, a ti rọju ju ọwọ si ẹ lati inu mọto a tun di iyọnu fun wọn. "Apanijẹ ikoko ni wọn ti i da awọ agutan bora. Ogun iṣọra ti a si le ṣe ki a maṣe ko agbako wọn ni pe ti aseko idibo ba to, ki a maṣe dibo fun iru wọn. Ti nwọn ba de aye Alakoso Ijọba tan, a ti mu wọn kuro ko ni ya a ṣe mọ. Oran a wa a di "Abamọ a ko ṣe e, a ṣe e tan o di aapọn."

KI a ro o ki a to ṣe e, o san ju ki a ṣe e tan ki a to ro o lọ. Awọn iwa ibajẹ ti a ni lati gbogun ti ninu ọran oṣelu wa ni a ti juwe wọnyi, ọna ti a si le fi gbogun-ti iwa ibajẹ na ki o le fi parun ni arin wa ni lati yan awọn Aṣoju Ẹgbẹ Oṣelu rere si aye Alakoso Ijọba wa, awọn ẹniti a ti mọ tẹlẹ pe nwọn ni ọgbọn iṣelu, nwọn mọ eto iṣelu, nwọn ni itara si ohun ẹdun-ọkan awọn ara ilu, nwọn ki i si ṣe ileri ki nwọn ma mu u ṣe. Gbigbọ ko si dabi gbigba, nitorina ẹ gbọ ki ẹ si gba.

# Oloye Dọkita Maja pari ija fun awọn ẹbi Kọsọkọ



EKO.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi ni awọn Oloye Dokita Akinọla Maja, Baba-Eko, J. Akanni Doherty Ọtun Eko, Abudu Smith, Osi Eko, Imam Lọya L. B. Agusto ati Oloye Alhaja Rabiatu, Iyalode Eko pari ede-aiyede ti o ti wa larin Oloye Aminu Kosokọ, Asajon Ọlọja Ereko ati diẹ ninu awọn ẹbi rẹ lati bi ọdun mẹfa sẹhin.

Imam Lọya L. B. Agusto ni o gbadura ni Iga Oloye na pe, ki Oluwa ran awọn lọwọ lati le pari ija na dada. Lẹhin ti nwọn ti gbọ tẹnu tọtun ati tosi ni nwọn wa da awọn ẹbi Oloye na lẹbi. Awọn ọkunrin inu wọn dọbalẹ, awọn obirin si kunlẹ nwọn torọ idariji lọdọ Oloye na, o si dariji wọn. Awọn ẹbi rẹ na ni awọn ko ni ẹnikan ti o ju u lọ laiye yi nitoripe on ni baba awọn ni gbogbo aye. Nwọn ni on nikan ni o ni ẹtọ lati ma a gba gbogbo owo-ile oye ti nwọn fi haya. Nwọn ni awọn ko ni ba a du u mọ awọn ko si ni yaju si i mọ lailai.

Oloye na ni lati fi han pe on ti dariji wọn on ko ni yọ wọn lẹnu lọwọ-lọwọ yi lati gba ẹgbaa pọnun o le diẹ (over two thousand pounds) owo ti Kotu ni ki nwọn san fun on lọwọ wọn, ati nitoripe on ri i pe nwọn koi ti ri aye rẹ lati san an nisisiyi. Oloye na dupẹ lọwọ awọn alatunṣe ọjọ na ki nwọn to tuka. Gbogbo awọn ti nwọn pe sibẹ le ni ọọdun enia.

## Akiyesi pataki

NINU ọrọ Olotu ti ọsẹ ti o kọja, nibiti a gbe sọ pe aseko Iforukọ-silẹ fun idibo !! Eko yio bẹrẹ ni ọjọ keji oṣu kẹta ọdun yi, ki iṣe bẹ ẹ (aṣiṣe ni.) Bi o ti jẹ gan an nipe ti Eko bẹrẹ ni ọjọ keji oṣu yi yio si pari ni ọjọ kejidiologbọn ti iṣe ipari oṣu yi kanna. Nitorina, a tun ran gbogbo ẹnyin ara Eko leti ki ẹ tete ma a lọ fi orukọ silẹ nisisiyi lọ ki aseko na to pari. Anu ṣe ni fun aṣiṣe kekere na. Ẹ wo oju ewe kẹjọ Iwe wa ọsẹ ti o kọja fun alaye kikun l'ede Oyinbo.

**Olotu.**




## Oloye Alakọla fi Ẹgbẹ Alakukọ silẹ

ILESHA.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejọ oṣu yi ni Oloye Daniel Ayẹni, Alakọla Abule Ikọla ni Iha Gusu Ilesha sọ fun gbogbo aiye gbọ pe on ko ṣe Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) mọ o si wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group). Babasalẹ ẹka Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) Abule Ikọla yi ni Oloye na iṣe titi di ọjọ ti o fi fi Ẹgbẹ Alakukọ na silẹ.

Ninu iwe ifẹgbesilẹ ti Oloye na kọ ranṣẹ si Ọgbẹni G. A. Arọmọlaran, Akọwe ẹka Ẹgbẹ Alakukọ Iha Gusu Ilesha ni o ṣe alaye wipe, lẹhin ti on ti wa pẹlu Ẹgbẹ Alakukọ fun ọdun mẹrin ni on ri oye pe ẹlẹtan gba a ni gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ. Gbogbo ẹbi on patapata si ti ba on lọ wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Action Group).

# KỌKỌRỌ ALAGBALUGBU OMI OKUN (6)



**Ọna marun ti ASHTON ati PARSONS fi mu ara ọmọde le ati mokun:**

1. Agunmu ipara ti Ashton ati Parsons a mã mu wọnran wọnran ode ara ọmọde wọle.
2. Agunmu ipara ti Ashton ati Parsons fi itura fun ẹẹ ehin ọmọde, a si fi ẹrọ fun ẹiẹ nigba hihu ehin.
3. Agunmu ipara ti Ashton ati Parsons a mã ki inu ri run wọ ni wara were; a si fi oluwa rẹ ni imikanlẹ.
4. Agunmu ipara ti Ashton ati Parsons a mã mu ọmọde sun daradara. Orun baji umu ara ọmọde ya a si lokun.
5. Agunmu ipara ti Ashton ati Parsons dara pupọ fun gbogbo ọmọde.

**ASHTON & PARSONS**



**ETU-OGUN FUN ỌMỌ-ỌWỌ**

*fun gbogbo igbona ehin ọmọde*

### AKIYESI PATAKI

KI nlo ma a ba itan mi yi bọ, mo fẹ ṣe alaye diẹ fun awọn oluka itan mi: Ekini:—Mo ti nsọ ti pe, pe emi ki iṣe Olotu "Irohin Yoruba", Ọgbẹni S. M. Ademuyiwa ni Olotu, on ni o si ni aṣẹ pe ki itan mi le ma jade lasiko ti o ba ri pe o yẹ, nipa pe ki itan mi ma jade loṣẹoṣẹ gẹgẹbi ifẹ inu nyin, o ku si ọwọ ẹnyin ati Olotu o.

Ekeji—ẹnikẹni ti o ba ni ohunkohun lati bere lọwọ mi, nipa itan mi ki o kọwe si mi gan, mo ti kilọ fun ẹnyin onkawe Irohin Yoruba pe ki ẹ maṣe yọ Olotu lẹnu mọ. Itan "Ajiran Ilu Oku" ti ẹ sọ pe ẹ nfẹ ni kikun lati oke dele yio jade fun tita ni osu ti mbọ; ẹ o ma a ri ipolowo tita rẹ ninu "Irohin Yoruba".

### ỌDẸ AMUJẸ BA IJAMBA PADE

Eyi ni idamu kini ati agbako ti Ọdẹ Amujẹ kọkọ ba pade, bi o ti nlọ ṣaṣaṣa, fusa ni "Ijamba" pade rẹ, aya re ja, o bẹrẹsi gbọn ririri, nṣe ni o kan nf'ehin lu ehin kekeke nitoipe ko le sọrọ—Ijamba rerin kekeke, o ni ha! a bi ọmọ enia abirun lori kọ ni eyi? Ọdẹ Amujẹ ko dalohun, o nwo ṣu u. Ko ni kun to, ko si ni dun to ti nko ba ṣapejuwe bi Ijamba ti ri.

Ijamba kuru, o ri ṣẹndi, ori rẹ ri godogbo, ṣugbọn oju mejeji ti o wa ni agbari rẹ yọ ṣọlọṣọlọ bi ina moto. Oluwa fun un ni agbara iriran to bẹ gẹẹ, ti o fi jẹ wipe o le ri ohunkohun ti o ba yọ ni ibuso kan si 1. Ohun ti o ya Ọdẹ Amujẹ lẹnu ni pe ti o ba mba enia sọrọ, ara rẹ a ma a yipada si oriṣiriṣi awọ bi ti alagẹmọ, eyi lo fun Ijamba lagbara lati ma a ṣe awọn ti o ba sunmọ ni jamba, nitoripe wọn kò le lete ri.

Lati ọwọ J. O. Shoyinka, Mushin

Ko ni ibi ti o ngbe ju iho apata lori oke tente lọ, irun ori rẹ funfun lau, o si mu hanranhanran bi waya (wire) ẹniti o ba fori sọ ni aiya di oku, ọmọ ika ọwọ ati ti ẹsẹ rẹ jẹ ogoji, ẹsẹ ọtun doju kọ iwaju, ẹsẹ osi doju kọ ẹhin, eyi ko jẹki irin rẹ ja u gara, nibu-nibu ni o ma nrin bi akan okun., atẹlẹwọ rẹ papa jẹ ekidã iṣo ẹniti o ba di mu, nṣe ni ara oluwarẹ yio bẹjẹ. Ni kukuru Ijamba haunhaun ni iṣe.

O tun bere lọwọ Ọdẹ Amujẹ, o ni awe kini o wa dehin sẹ? Ọdẹ Amujẹ ko dalohun, Ijamba ni adahun ma dahun rẹ, agunla aguntẹtẹ pẹnpẹnrẹn inu rẹ, iwọ ti o ko dahun nisisiyi, ni yio dahun ni kiamọsa laipẹ. Teti silẹ ki o gbọ ohun ti ngo sọ fun ọ.—Emi ni Ijamba ẹniti o fi abẹ apata ṣe ibugbe, odindi kiniun bọlọjọ kan ni mo le kuro ninu iho yi, ki nto sọ di ibugbe mi, nko si ni ọrẹ miran

**Wo oju ewe kejo**



Emi ni Ijamba ẹniti ko fi ibikan ṣe ibugbe a fi Agbedemeji ọrun on aiye.

# O nsare rin gan an

FUN iranlọwọ ati iṣẹ ṣiṣe dada fun awọn onisowo ti nwọn nranṣẹ ọja wọlu ati awọn ti nwọn nfi ọja ranṣẹ sẹhin-odi, Palm Line "nsare rin fan an" Gbogbo ọkọ akẹru rẹ yiyara asekoyi ni o ti pese irinṣẹ ti o le ma a fi ko oriṣiriṣi ẹru ọja tita bi irinṣẹ-ẹrọ ati awọn ọja tita miran. Pẹlu iyara ati itọju ni nwọn fi nfi ọkọ akẹru kookan nṣiṣẹ. Palm Line nṣe igberaga lori iṣẹ rẹ ti o darajulọ nipa iriri ati imọ dada nipa awọn ohun ti Ọlọkọ akẹru Iwọ-Orun Afrika nfẹ.

AWỌN OKỌ ELEFIN TI AWỌN OYINBO ỌLỌKỌ PALM LINE ṢẸṢẸ FI KUN ỌPỌLỌPỌ ỌKỌ TI NWỌN TI NI TẸLẸTẸLẸ RI NI:



BAMENDA PALM

ELMINA PALM

KATSINA PALM





Iṣẹ wa ni lati maa ko gbogbo ẹru nyin

Ko o wa fun PALM LINE

J2667

# Akiyesi awọn Awo-Irawọ nipa Ọjọ-Ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣelẹ larin ọsẹ yi, February 8th—14th, 1959.

## CAPRICORN

(DEC. 21ST—JAN. 19TH)

Ọsẹ yi le jẹ ọsẹ pataki lori awọn oran owo (money). Yiyẹ-adehun ti yio ṣelẹ si ẹ ni ibẹrẹ ọsẹ yi, yio mu ẹ tun eto ṣe ti yio mu itẹlọrun pupọ wa. Maṣe jẹki awọn ero lori oran ara rẹ ba awọn eto ti o ti nṣe tipẹ-tipẹ jẹ.

## AQUARIUS

(JAN. 20TH—FEB 18TH)

Wa a mọ pe ibatan kan ko le ni ara da aye ti nkan wa ni inyi. Bi o ba wa imọran ti o dara, bọya wa a ri i lọdọ ọrẹ kan ti o wa ni aye pataki l'aye yi. Nipa ohun ti o jẹmọ owo (money), asiko ọrọ niyi ati atunṣe ti o fẹ han.

## PISCES

(FEB 19TH—MAR. 20TH)

Olufẹjumọ rẹ ti npọsi i, wa a si mọ otitọ yi ni ipari ọsẹ yi. Lo o fun anfani imọ ti o dara larin ẹbi rẹ ati ibisẹ rẹ pelu. Wa a ṣe orire nipa owo (money), bi ọdun yi ba fẹ pari, ni ọjọ 'Ru (Wednesday).

## ARIES

(MAR 21ST—APL. 20TH)

Ma a ṣe eto titun rẹ lọ lati yi i pada pẹlu gbogbo awọn iṣoro ti o le ti idi rẹ yọ. Maṣe jẹki alekun bukata ba itara rẹ jẹ. Ni ipari ọsẹ yi wa a ṣe adehun kan ti yio tẹ ẹ lọrun lori iṣẹ kan tabi ki nwọn ṣe awọn ileri ti yio mu owo (money) wọle fun ẹ larin ọsẹ diẹ.

## TAURUS

APL. 21ST—MAY 20TH)

Aseko iṣoro yio dopin ninu ọsẹ yi. Nitori, o le sọ asọ diẹ lori bi owo ti ṣe njade, o ko ni i ṣe iyemeji rara nipa aseko ti o mbọ. Ọpọlọpọ nkan dada ni yio to ẹ lọwọ titi ọjọ meje nipa iwa rẹ ati itẹpamọṣẹ rẹ.

## GEMINI

(MAY 21ST—JUNE 20TH)

Bi o ti wu ki aidọgba nkan le ba ẹ ninu jẹ to, wa a mọ nipari oṣu yi pe, awọn igba iṣoro ti kọja. Iri rẹ bi ọmọ enia jọ awọn ti o le ran ẹ lọwọ, ninu aiye yi, lọju gan an. Bi o ba jẹ aṣoju ẹnikan ti aye si gba ẹ, asiki a ti gbeyawo yio fojuhan titi ọjọ Abamẹta Saturday).

## CANCER

(JUNE 21ST—JULY 20TH)

Ero nipa ọran ẹbi yio pọ fun ẹ nigbogbo ọsẹ ti o mbọ yi. Bi o ba ṣe iyemeji, kọkọ ṣe aṣaro lori ọran ti awọn ọdọ ki o ti ṣe aṣaro lori ti awọn ti o ju wọn lọ. Lẹta ilaja ija nikan kọ ni yio pari ṣugbọn yio ṣ'anfani l'ọna owo (money) pẹlu.

## LEO

(JULY 21ST—AUG. 21ST)

Nikẹhin wa a mọ pe aseko ifaiyabalẹ mbọ. Ọsẹ yi ni ko ni si ija ninu ile ati hilahilo fun ẹ mọ. Iyipada diẹ ṣi ku ti o ma a ṣe, lati igbana titilọ wa a bẹrẹ si gbadun aiye rẹ, irufẹ eyiti o ko ti gbadun rẹ fun igba diẹ ri.

## VIRGO

(AUG. 22ND—SEP. 22ND)

Wa a bẹrẹ iṣẹ titun kan tabi ki o yi eto iṣẹ rẹ pada Nitotọ bukata pọ, iba ni wahala rẹ yio mọ nipa owo. Ọrẹ aṣẹṣẹyan kan yio di pataki bi awọn ọsẹ ba ti nkọja. awọn ọsẹ ba ti kọja.

## LIBRA

(SEPT. 23RD—OCT. 23RD)

Ọrẹ tuntun kan yio ba ọ ti yio jẹ oninufufu-enia, ṣugbọn o ni ifẹ ti o daju. Maṣe binu ju tabi daamu nipa owo (money). Bi o ba mu suuru ti o si le ṣe oyaya, ajumọṣepọ nyin yio yọri si dada larin oṣu diẹ.

## SCORPIO

(OCT. 24TH—NOV. 22ND)

Awọn iyipada ti yio kan ẹbi rẹ tabi aye ibugbe rẹ yio ṣelẹ lọsẹ yi. Iṣesi awọn ẹbi rẹ le kan ẹ diẹ, iṣofintoto ti o ko fẹ le mu ẹ binu. Ọsẹ yi dara fun eto ẹgbẹ tabi fun adehun ti o jẹmọ ti ere-ọmọge.

## SAGITTARIUS

(NOV. 23RD—DEC. 20TH)

Ọkan rẹ ko ni si laye hila-hilo mọ nipa aisi owo (money), ki ọsẹ yi to pari. Wa a mọ gan an nisisiyi ohun ti yio ṣe ẹ ni anfani pupọ lati ṣe ninu ọdun 1959. Awọn eto lati rin irin-ajo tabi lati gba agbaṣe-iṣẹ titun kan le daru lairotẹlẹ.

**Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"**







Inu nrun un, ko le jẹun, ko le sun ati pe irora na wọ ọ lara. O ni aran-Iuruku ni.

Nisisiyi o ngbadun dada, O njẹun dada o nsun dada o si ngbadun aiye dada. O ti lo egbogi Helmezine ni.



**FI ORU-MỌJU ỌJỌ KAN LE GBO-GBO ARAN-EEPA INU RẸ JADE NIPA LILO EGBOGI**

**HELMEZINE**

*AGBAYANU EGBOGI ATARAN-JADE ONI-GẸẸ KAN*

Awọn Alagbata: Allen & Hanburys (Nigeria) Limited, Hanbury House, Tinubu Square, Lagos. P.M.B. 2310 Lagos. Telephone: 23888/9
Telegrams: Allenburys Lagos
Also at P. O. Box 543, Ikot Ekpene Road, Aba. Telephone: 240.




# Kọkọrọ Alagbalugbu

(Lati oju ewe karun)

ju agbako lọ, o fẹrẹ de ba ọ nihin. Emi ni gbogbo ọmọ ẹda-ọmọ adamọ, ma fi ọrọ rẹ sinu adura pe, Ọlọrun ma jẹki a ri jamba o, Ọlọrun ma si jẹki a ko agbako o, eyi ni ọrẹ mi. Nisisiyi o ti ri Ijamba, o si ti pade agbako, ewo wa ni ṣiṣẹ o? ọmọ enia ti mo ti ṣe ni jamba ko lonka, awon ti o si gba Bode mi yi kọja bi tirẹ yi, si ti ku iku oro, nko loju anu, mo tọro-rẹ lọdọ Ọlọrun, ko fun mi ni, nko lọmọ, bẹni nko lọmọ-iya tabi iyekan kini o le mu mi loju anu? Ọkunrin.

Bi o ti nsọrọ ni ọmọ Ọdẹ Amuje bẹrẹsi gbọn, aiya rẹ nja, ọkan rẹ koi ti gbo nitoripe ọmọde ni. Ijamba ni loni kiku n'iwọ y'o ku, b'o ti nsọro lowọ ni agbako de. Iri ati wiwo agbako tilẹ tun dẹruba enia ju ti Ijamba lọ. o gun, o ri tanbọnin, igbaaiya ni o pọ si bi ti Kiniun, gbi ti o sọ apo ti o wa ni ejika rẹ kalẹ, o ni ha! o rẹ mi, bayi ni o fi sun lọ finrinfinrin, emi ti o njade ni iho imu rẹ lọ aṣọ mọ Ọdẹ Amuje lara, ihanrun rẹ ko ṣe f'ẹnu sọ, ẹniti o wa ni idaji ibusọ ngbọ.

Nigbati Ọdẹ Amuje wo, o rora sọ ni ọkan rẹ pe, iku de, o to ko ji, ko ji, inu bi Ijamba o lu pẹpẹpẹ, o ni agbako dide, dide, ki a tete ṣe idajọ fun ọkunrin yi, ati ọmọ,rẹ, ṣugbọn ko ji. Ijamba ṣẹṣẹ wa ranti pe kumọ onirin ni won ma fi ji ti o ba sun. Ijamba fa kumọ onirin yọ, o bẹrẹsi fi lu ni atari ko, ko, ko, nigbayi ni o ṣẹṣẹ to wa "yan ho o", jagunlabi rọ bipa, ni o ba dide kan. Dide ti o dide, o ni Ijamba o, Ijamba o, gbogbo ara lo



ODE AMUJE

* * *

wo mi o, jọwọ fun mi ni oogun ti o dara o. Ijamba tun fa kumọ yọ, o bẹrẹsi lu orikerike ara, o lu kisa si lara, o ni ha! Ijamba o ma ṣeun, ṣeun o ku ajo mi o, ara mi wa le dada nisisiyi mo dupẹ o. Ohun ti oju Ọdẹ Amuje tun ri yi tubọ mu ki ẹru ba a.

KOI TI PARI

## Awọn Musulumi Igede Ṣe Ikore

IGEDE-EKITI.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni awọn Musulumi Igede ṣe ajọdun ikore alarinrin. Awọn alaga ọjọ na ni Oloye Olufinba, Ọgbẹni S. A. Sule, Iya-ẹgbẹ ati Adiatu. Nwọn nawo pupọ Ọgbẹni M. Y., akọwe agbe ṣe gudugudu meje. Ọgbẹni J. A. Adewunmi fi kalamu re dabira

Irohin ko to afojuba ni aṣeyẹ ọjọ na. Aṣeyi ṣamọdun o.

* * *

Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun




Fun ajinde ara ti o daju ati agbara fi Liver Salt ti o nta wọnin-wonin bẹrẹ ọjọ rẹ. Ṣa bu ẹkun ṣibi kekere meji sinu ẹkun ife omi kan, mi i papo ki o si gbe Andrews rẹ mu bi o ti nho susu.
Didun lẹnu Andrews ngmu ẹnu ya akọtun dada o si ngmu inu balẹ. O nfun ẹdoki lagbara. O nse iranlọwọ kiko idọti inu jade deede lojojumọ. Andrews a ma a siṣẹ pelu irọrun ṣugbọn ni pẹlẹpẹlẹ laisi inira lẹhin-lilo-rẹ. Fun imọtoto inu fun agbara ati okun, ko si ohun ti a le fi we ife Andrews kan l'arọ.

O DUN-LẸNU
O nta Wọnin-Wọnin . . . O Ntẹjẹṣẹ!
Agolo Tẹlẹmode—3s. 6d. Agolo Imudani—2s. 3d. Agolo ka lo o wo—1s, 6d.




ỌLỌGBON ÀGBÈ NGUN RALEIGH

Pẹlu irọrun ni ọlọgbọn àgbè ngun Raleigh de'bi iṣe. Ko gba'gbara, ko gba'siko, nitorina o le kọ ebe lọpọlọpọ, ko si gbin ohun ogbin pelu. O nko ohun titẹ lọ ọja laifi ṣ'alaru. Nipa bẹ yio ma pawo pupọ.

O GBỌDỌ *gun Raleigh*

GBOGBO IRIN KEKE
RALEIGH
LO RỌ

# Akolo-Mọmọ f'ilẹ ṣ'aṣọ bora

ODO-ẸRI.

OSE! "Iku pa Babalawo bi ẹniti ko gbọ Ifa, iku pa Onisegun bi ẹni ti o gb'ogun Iku pa Akolo-Mọmọ bi ẹniti ki i ki Ọlọrun Ọba".

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ ke-rindinlogun oṣu kọkanla ọdun ti o koja yi (1958) ni [illegible]ẹnla ṣe, ti irohin ọfọ nla gba gbogbo ilu kan pe, Ọgbẹni Akolo-Mọmọ lọ jẹ ipe Ọlọrun. Ologbe yi jẹ pataki kan ninu Ẹgbẹ Temidire ati Ẹgbẹ Amulu-dun Odo-Ẹri, o jẹ alakikan-ju ati olotitọ, o ni oju-anu pupọ lati ma a ran awọn talaka lọwọ, o si l'ẹmi ikoni-mora bẹ ẹ na ni o si tun jẹ olufọkansin.

Aisan ọjọ meji pere ni o mu Ọgbẹni Akolo-Mọmọ lọ nigbati o di ẹni ọdun mọ-kandinladorin (69 years) laiye, gbogbo ilu Odo-Ẹri ni o parọrọ nigbati nwọn gbọ iku Ọgbẹni Akolo-Mọmọ, nṣe ni awọn onimọto, oni-baisikulu, ẹlẹsẹ ati gbogbo enia nrọ lọ sibẹ lati ri i daju pe tootọ ni ọfọ nla ṣe Ẹgbẹ Temidire ati Ẹgbẹ Amulu-dun ati gbogbo ilu Odo-Ẹri.

Nigbati Ọgbẹni M. Ade-gboye gbọ ni Eko, o fẹrẹ sare de Agege ki o to ranti wọ mọtọ, ẹsẹ gbogbo awọn enia pataki pataki ni o pe si ibi isinku rẹ, bẹni ọpọlọpọ ti o gbọ t nwọn sare wale lati idale, nwọn si sin oku rẹ pẹlu ẹyẹ ati iyi, irohin ko to amojuba ni. Adura gbogbo tomode tagba Odo-Ẹri ni pe, ki Oluwa da awọn iyawo rẹ si ki O si fi awọn ọmọ rẹ se iru, ki O si wu Ọlọrun ni-nu Anu Rẹ lati gbe iru enia ọẹ ẹ dide ti yio rọpo rẹ larin Ẹgbẹ Temi-dire ati Ẹgbẹ Amuludun. Amin.

Ẹ MA A POLOWO ỌJA NYIN SINU IWE
Irohin Yoruba


IṢẸ TI A RAN SI Ọ



Emi ni Apọnti to pọn GUINNESS STOUT
Nigbati ara mi ba gbona ti ongbẹ si ngbẹ mi Emi ama fẹ Guinness tutu ṣugbọn Emi mọ pe GBIGBONA tabi TUTU Guinness dara fun mi otitọ si ni!

B.A. B.Sc. M.B.E.
Olori Apọnti-A-Guinness Son & Co.

GUINNESS dara fun ọ
Gbigbona tabi Tutu
gẹgẹbi IWỌ bati fẹ

